# OKU TIKO KU S'OMI NM'OKUNKUN NI SARE



SEE YOU PAY THE CORRECT PRICE.

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO



AWOGBA Omode fun Obi, Ejo, Iku - ehin, ... Ko Tun Ni Ile Egbogi — ISE — Isdasare Okebola, Ibadan. 116, Great Bridge St LAGOS

VOL. IX No. 530. ELETI - OFE LAGOS, SATURDAY, JULY 27, 1957. KOBO MEJI (2)

## Oku Tiko Ku S'omi Nm'okunkun Ni Sare

Laipe ojo yi ni a ni anfani lati ba won gbe oku enl're kan lo si ite - oku lati lo re esikusile kerofo ara oku na te sinu iboji. Nigbati a ri opolopo iboji awon ti awon je enia nla-nla, awon ti omo tabi ebi won ra ile ko ile l'ori iboji won, enu kekere ko l'o ya wa.

### OKU NLUWE NINU IBOJI

Opo ati ogunlogo ninu awon iboji oku wonyi ni o ti fo ti ojo si ti ro kun inu won, ti awon omo oloku tabi ebi oku wonyi ko bikita lati maa se abewo won fun atunse, eyi mu enia ronu wipe nigbati enia ko ku s'omi ki o wa je wipe lehinti awon ti sin oku re tan ti awon si se inawo ribiribi le lori nipa ase fun jije ati mimu fun awon enia de'pe ti a tun kole le ori iboji oku enibe, ni oku na yio tete wa bere si luwe ninu omi ti ojo ro kun inu iboji to ti fin sisale.

### IBUKUN NI IRANTI OLODODO

Beni oro Olorun wi. Enia o ba ranti oku re nipa sise itoju iboji won l'orekore, yio ri ibukun gba. Lona keji ewe, ohun itiju l'o nilati je fun omoluwabi enia wipe iboji iya tabi baba won ti fo ti ko si ri atunse ti o fi di ohun apewo fun gbogbo enia ti o ba ti gbe oku lo si ite - oku.

(Wo iyoku loju ewe keje)

THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited
Incorporated in Nigeria in 1933
Paid up Capital - £1,190,800
Bankers to the Western Region Government of Nigeria.
HEAD OFFICE
87, MARINA, LAGOS, NIGERIA
22 Branches throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO, BENIN-CITY, WARRI, SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS.
LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell
Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams: Natbanigor, London.
Head Office Representative in London
Ernest Olubunmi Obasa—Porter
CORRESPONDENTS
NEW YORK PARIS HAMBURG

## Ejo D'atun Ro.



Eniti a nwo yi ni Alaiyeluwa oba Eko, Kabiyesi, Adeniji Adele Keji. On ni omo Oyekan kan ti awon npe ni Adeyinka ate kaarangbon ni lori ohun ti ko nse lai ti enikanseso, ti o je ohun fun Ade ati ti aromodomo re.

Nwon ti ro ejo yi ninu kotu Ganran nilu Eko, oba Adele lo jare, nwon ro o niwaju adajo meta, Oba lo jare. Nwon tun gbe ejo lo si Privy Council nilu Oyinbo, oba Adele tun jare - sibe omo Oyekan ni ejo na koise on lorun ayafi bi nwon ba tun ejo na ro.

Lojo Monday 29th osu July, 1957, ni nwon o tun ejo na ro. Loya omo Oyekan ni Ogbeni Diagle Post. Loya ti oba Adele ni Ogbeni Mekeuan.

## Olopa Mu Alhaji Dantata

KANO. "Ipeleje oro ni egbin" gegebi Owe Yoruba, iyanu nla ni yio je fun enikeni lati gbo wipe Olopa oba nilu Kano, mu omo Ologbo Alasan Dantata, olowo arakuyama nile Hausa ti oruko re nje Alhaji Mahmood Dantata.

### KILO FA ?

A gbo wipe awon olopa fi sun esun sise owo aiyederu, Koroasi oni Poun marun-marun Gbogbo iwe owo aiyederu ti awon ri ko sinu ile Alhaji Mahmood Dantata je mejidinlegberun (998) oni poun marun-marun, ati Ero isewe owo oni poun marun, meria ni awon ba ninu ile re.

Ni akoko, awon gba iduro fun, awon si tun mu wipe awon ni ifura si wiwe nile re. Adajo ni ki awon fi ni itmole di ogunjo osu August, 1957 nigbana ni rira ejo re yio bere.

# LAGOS RACE CLUB AUGUST MEETING

## Saturdays 3rd, 10th, 17th and 24th August, 1957

| | FIRST DAY | START |
|---|---|---|
| RACE No. 1 | Ten Furlongs Handicap Bottom Division | 3.00 p.m. |
| RACE No. 2 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 3.35 p.m. |
| RACE No. 3 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 4.10 p.m. |
| RACE No. 4 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 4.45 p.m. |
| RACE No. 5 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 5.20 p.m. |
| RACE No. 6 | Eight Furlongs Handicap Top Division | 5. 55 p.m. |
| RACE No. 7 | Open Race — Eight Furlongs Top Division "A" | 6.30 p.m. |

| | SECOND DAY | |
|---|---|---|
| RACE No. 8 | Five Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 00 p.m. |
| RACE No. 9 | Five Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 35 p.m. |
| RACE No. 10 | Eight Furlongs Handicap Middle Division | 4. 10 p.m. |
| RACE No. 11 | Eight Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE No. 12 | Eight Furlongs Handicap Middle Division | 5. 20 p.m |
| RACE No. 13 | Polo Scurry | 5. 55 p.m. |
| RACE No. 14 | Ten Furlongs Handicap Top Division | 6. 30 p.m. |

| | THIRD DAY | START |
|---|---|---|
| RACE No. 15 | Seven Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 00 p.m. |
| RACE No. 16 | Seven Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 35. p.m. |
| RACE No. 17 | Ten Furlongs Handicap Middle Division | 4. 10 p.m. |
| RACE No. 18 | Ten Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE No. 19 | Ten Furlongs Handicap Middle Division | 5. 20 p.m. |
| RACE No. 20 | Five Furlongs Handicap Top Division | 5. 55 p.m. |
| RACE No. 21 | Open Race - Ten Furlongs Top Division "A" | 6. 30 p.m. |

| | FOURTH DAY | |
|---|---|---|
| RACE No. 22 | Nine Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 00 p.m. |
| RACE No. 23 | Nine Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 35 p.m. |
| RACE No. 24 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 4. 10 p.m. |
| RACE No. 25 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE No. 26 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 5. 20 p.m. |
| RACE No. 27 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 5.55 p.m. |
| RACE No. 28 | THE COMMONWEATH STAKES Twelve Furlongs —Top Division | 6.30 p.m. |


## Idahun Si Ibere Ogbeni Jay

Olotu,

Jọwọ, gba mi laye ninu iwe rẹ lati fesi si ọrọ eniti ope ara rẹ ni R. A. Jay, ti itu Martins, tio jade ninu iwe rẹ ọjọ Saturday, July 6th, 1956, ni oju ewe kẹta.

Mo fẹ ki Jay la ye, wa idi ti ofi sọ wipe o yẹ ki Owu ati Oke-Onigbin wa ni irẹpọ, nitoripe emi gẹgẹbi ọmọ Owu ko ro wipe ede-aiyede wa larin Owu ati Oke-Onigbin nigbakan ri. Nitorina, inu mi yio dun bi Ọgbẹni Jay ba le sọ fun mi, ede-aiyede to ba wa ni arin Owu ati Oke-Onigbin, ati ohun ti o fa ede-aiyede na ati igbawo ni o bẹrẹ.

Mo fẹ ki ọgbẹni R. A. Jay laye wa bi o ti ṣe mọ wipe ija wa larin Kiriyo ati Imale Owu nitoripe emi to jẹ ọmọ Owu le sọ gbangba pe kiriyo ati Imale Owu ko ja rara, inu wa yio si dun bi ọgbẹni Jay ba le sọ fun wa bi on ti ṣe jẹ ni Owu titi ti ofi mọ wipe ija wa larin Kiriyo ati Imale Owu, nitoripe mo mọ dajudaju pe ko si ọmọ owu ti o njẹ R. A. Jay. Bi o ba si jẹ ọmọ Owu na lo ra Oruko fun ara rẹ bẹ, kinilẹ ti iru enia bẹ ko fi le ṣe atunṣe ohun to ri ti ko ba oju mu ninu ilu ara rẹ to fi di wipe tiI o nkọ sinu Iwe Irohin.

Mofẹ ki ọgbẹni R. A. Jay laye wa ohun ti awọn ile ilu Owu sọ wipe ni on yio pọun kọkan ṣe ki awọn to ma da lẹhin igbati awọn ti pari Ọja Mọto lati Oke-Onigbin si Owu tan. Njẹ Ọgbẹni R. A. Jaw da njẹ owo na ?. Bi o ba si se wipe on na da ninu owo na, kinilẹ ti on kofi le tere lọwọ Akapo ilu Owu tabi lọwọ awọn Igbimọ ilu Owu iye ti owo na da. Dajudaju, ọgbẹni ti on pe ara rẹ ni R. A. Jay ni lati jẹ Ọlọtẹ ati Adaluru enia lo fi le wipe awọn nreti esi ọrọ na ki oto di giga. Mofẹ ki ọgbẹni Jay lo da gbogbo ọgbọn inu rẹ lati le jẹki ọrọ na di giga Bi Oluwa si ti ntẹ yio ba awọn Igbimọ Ilu Owu nibẹ. Nitorina, Ọgbẹni Jay tete gbiyanju lati jẹ ki ọrọ na di giga o.

Mo dupẹ lọwọ Olotu tio gba mi laye, oko Ọba ko ni ṣa nyin lọṣe o

Mo duro bayi,

Emi ni Akọwe;

Igbimọ Owu.

Yusufu Ọlatunji

14 Aibu St. Lagos.

## Akiyesi Pataki

A fi eyi kede fun gbogbo ẹnyin Asoju Iwe Irohin wa nile Yoruba, l'oke Ọya, nile Ibo, l'oke Okun ati aju Oyinbo wipe enikẹni ti ko ba fi owo ranṣẹ, ao ko oruko rẹ fun Lọya Eleti Ọfẹ, ao ba ṣe ẹjọ ao si gba owo irin ese lọwọ wọn.

OLOTU


## E ma ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Ki E Si ma polowo Oja Yin Sinu Re.

SECOND-HAND CLOTHING:-

| | |
|---|---|
| Women's Long Overcoats | 2/6d. |
| Women's Short Coats | 1/6d. |
| Women's Dresses and Frocks | 1/- |
| Women's Skirts | 1/- |
| Men's Overcoats, | 6/- |
| Men's Raincoats, Cotton and Gabs mixed | 2/6d |
| Men's Jackets | 2/- |
| Men's Waistcoats | 6d |
| Men's Felt Hats | 1/- |
| Police Helmets | 1/- |

Prices quoted ex Warehouses C.I.F. charges extra, Wholesale quantities only Immediate attention, Write for full prices list. Organs £10 Radiograms £10, Pianos £10 Typewriter £10. Sewing Machines £10.

H NEWMAN & CO. (MERCHANTS) LTD. 88/92, ELIZABETH STREET MANCHESTER. ENGLAND

# Alapara Ibadan Nki Nyin O

Enyin ore mi, nitoto mo ni awon ara wa ti o lo si Ilu Oyinbo fun eto ilu mu nkan mirin-mirin bo fun opolopo awon eka ilu ti o wa ni Naijiria. Awon ala-mulegbe mi ni Ila-orun (Eastern Region) ri ti won se.

OYE WOLE DE O

Azikiwe ti mu igbimo Oloye wa fun awon ala-mulegbe ni ilu Obi nibiti Iye Ogongo ta ju ileke Segi lo.

Ogbeni Lennox-Boyd, akowe agba ilu oyinbo ni ko da on loju pe awon oloye wa ni Ila-orun-bi o ba si je wipe won wa, ogota ninu awon asoju won ni on a fe ki won jo ma se igbimo po.

Akowe Lenox-Boyd, Oloye wa nilu Ibo, bi a ti se nfi won je al o yato. Nigbati emi Alapara Ibadan papa wa ni Onitsha, won fi mi je Ogbuefi larin awon odomokunrin. Iye Ogongo kan ni mo ni lati ma fi si fila mi; owo ti o na mi ko ju adajo poun lo-eyi ti e npe ni apokan-abo. Elemiran nna to ede-gbeta poun ki a to fun loye tire.

OYE KAN EMI ALAPARA.

Bi iye inu fila re ba ti po to ni ao se mo bi inawo oye re ti to. Nitoriyi ti emi ti ni iyawo ti mo si ti bi omo si Onitsha, o ye ki nwon fi emi na je Obi-eyin-Oba I. si ileto kekere kan ti a npe ni Oba leti Onitsha. Oye kan emi na o-

S'APON LORE

Oro iyawo ti mo mu enu kan yi lo je kin nnira ofin tuntun ti o stoe jade nipa a nfe iyawo nile Ibo. Aiye ti lu jara, owo iyawo ti dire si Ila-Orun. Won ti se awon apon lore. Owo iyawo ti kuro ni igba poun (eyiti o mo iwe) tabi ogofa poun (emidan ti ko kawe), o wa di poun marun titi de ogbon poun-gegbon owo iyu-gbo, baba gbo, ko gbodo ju oke mejo o i le

(Wo yoku loju ewe kerin)

AKIYESI PATAKI

Esikeni ti o ba fe ra Iwe Irohin Eleti- Ofe Ki o lo si Idi Moto, Ogunpa, Tabi Lodo Asoju Wa, Ni 107, Oke Padi, l'egbe Sosi Aguda Nilu Ibadan.



# E L E T I Ọ F E

A-NJU-WỌN KO SE WI L'BIJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos "ELETI - ỌFE LAGOS"

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. IX. NO. 530, LAGOS, SATURDAY JULY 27. 1957


## E Se Iranti Awon Oku Yin

A fi wosika wa ọsẹ yi ṣe iṣiti fun gbogbo ẹnyin to ni oku lọrun, paapa awọn ẹniti oku na fi ogun silẹ fun, owo tabua-tabua. Iru awọn ọmọ oloku bawọnyi a ma jo, awọn o si ma yọ nigbati oku wọn ba ṣẹṣẹ ku, yala iya ni tabi baba. Nwọn o pe ẹgbẹ ati ọgba nwọn o ra ọti. nwọn o se onjẹ, bi owo na ba si pọ to nwọn o ra iboji fun oku na nwọn o mọ simẹnti le lori.

Ṣugbọn lẹhin ti ọdun kan ba ti kọja ni awọn ọmọ oloku nwọnyi ko ni ranti oku wọn mọ. Ẹnikẹni ti o ba lọ si itẹ oku ni ikoyi tabi lẹhinkule Abari yio gba wipe awọn ọmọ oloku nwọnyi ti gbagbe oku wọn.

Ọpọlọpọ iboji lo ti jin sinu ti agbara ojo si wọjọ pọ sinu rẹ. Iboji oku miran ti ya, omiran jin sinu tobẹ bi ẹnia ba rọra sunmọ eti rẹ, ti o si yọju, yio fẹrẹ ma ri aṣọ ti oku na gbe lọ si ọrun.

Kini ohun na, ẹniti, o ba mọ wipe on ko ni ri aye tọju iboji awọn oku rẹ, tani ẹniti o ran oluwa r nișẹ lati mọ iboji? Itiju nla ni yio si jẹ fun awọn ọmọ oloku, ti nwọn o ma wọ aṣọ olowo iyebiye kakiri, ṣugbọn ti nwọn ko ni bikita fun oku awọn ti o ṣẹ wọn silẹ.

Iwe mimọ sọ wipe ibukun ni fun awọn ẹniti o nranti awọn oku rẹ ti o ti ku s'ọrun, ti o si nṣe ẹhin wọn dara-dara; kiyesi awọn angẹli lọrun yio ma ranti oluwa rẹ si ohun rere pẹlu.

Ẹ ranti Awọn oku yin


## Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin abiyamọ ẹ wa ra ỌMỌRELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama jẹ ki ọmọde ri orun sun daradara o dara fun otutu, ikọ ati orișiriși arun miran ti o ma mba ọmọde ja ni asiko ebin. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo egbogi yi fun ọmọ wọn ti wọn si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE

(Sile Meji Abọ 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lọdọ

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS.


## Awon egbe W. H. O. gbogun ti Ogodo

OGOJA. Awon egbe kan ti a npe ni World Health Organisation ti fi lo wipe, arun ete, arun Ogodo ati arun masun – masun poju nile Nigeria ati wipe awon ti setan lati gbogun ti awon arun na.

Laipe yi awon agbajo egbe Onisegun Oyinbo bere ise won ni agbegbe Ile Ogoja, a si gbo pe, oke meta enia (60,000) ni nwon yewo ti nwon si se itoju won,

Awon arun pataki ti o wopo nilu yi ni arun Ete, arun Ogodo ati arun masun-masun, Opolopo enia ni arun yi ti pa danu.

## Alapara nki nyin o

(O bẹrẹ loja ewe kẹta)

șile meji lọ. (pọun meji ati sille meji).

Emi na ko nipẹ lọ si Aba nilu Nguwa lati lọ fẹ iyawo kan si. "Mẹ", ni Ọlọrun wi, ko npọ ju. Ọrẹ mi Aja Nwachuka, ẹ gba mi ni ana o.


HINDU SANKARA'S

Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas. Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

Enclose 4/- money order by Air Mail for Catalogues and Literature.

HINDU SANKARA, 20 Montpelier Row, Blackheath, London, S.E.3, England



Bi o ba fe je Gbajumo

Ra BICYCLE

Siga Gbajumo ile Nigeria.



# Alafin Oyo di odun kan lori oye



OYO. Alaiyeluwa Bello Gbadegesin Ladigbolu keji, eniti o je oye Alafin Oyo ni 23rd osu July 1956, on lo nse awuye-wuye ajodun odun kan ti o ti g'ori ite oba.

Ajodun na yio mu riwo-riwo ljo dani, ninu Afin, ati kakiri igboro ilu Oyo. Oba yi yio pin owo sinu awon Sosi ati si inu awon Mosalasi lati fi ba on dupe lowo Olorun fun ore re ati anu re latigba ti on ti g'ori oye.

Awon enia pataki-pataki yio wa sibi ase na lati Ibadan, Eko, Ogbemoso, Abeokuta, Ijebu, Ife, Oshogbo, Ilesha, Benin; Otta, Warri, Abo, Asaba, Ilaro, Iseyin, Ede ati Ejigbo. Ni ale ojo na ni awon olola, gbajumo ati awon ijoye ilu yio se faaji ni gbogan igbadun ti a npe ni Summer Garden. Ojo na dabi eyiti Alafin ngbeyawo. Kabiyesi! ki ade pe lori, ki bata pe lese, Alaiyeluwa, Kabiyesi!

## Esin Ati Otito Iwa Ni Olorun Fe

(Lati ọwọ Lemọma Ajakuta)

Ọlọrun paṣẹ fun Anọbi Adamọ ati Awawu wipe ẹ ma lọ sile aiye, ki ẹ ma jẹ, ki ẹ ma mu; ki ẹ ba ara yin bimọ, ki ẹ si ma gbe win lori ilẹ aiye. Ṣugbọn ẹ maṣe gbagbe wipe, Emi ni Ọlọrun, ko si tun si ẹlomiran mọ; ẹ ma sin mi ninu iwa mimọ ki ẹ si ma fi otitọ ati ododo joba lori ohun gbogbo ti o mbẹ lori ilẹ aiye.

Ọlọrun ko gbe iṣẹ nla kọkan fun won ṣe, bikoṣe wipe, ki a ma sin on, ati ọkunrin ati obinrin. Ọna ti o si dara ti enia fi le sin Ọlọrun ni eyiti o fi ran Anọbi Muhamad. Eniti o ba okirun, a gbagbọ pe aleyini nala Ọlọrun.

Ogunlọgọ awọn enia lo nfẹ sin Ọlọrun ṣugbọn awọn ko ni alafia to lati dide duro fun iṣeju marun sibẹ, eyi ko wipe ki awọn maṣe sin Ọlọrun. Bi iduro ko ba ṣe ṣe; ki eni na joko sile, lori apoti tabi lori ẹni tabi awọ. Bi eyiyi ko ba si ṣeṣe ti iduro pelu ko ṣeṣe, fi ori nikan ki i.

Bi eyi pelu ko ba ṣeṣe, fi ika ifabẹla ki i, bi amodi ko ba jẹki o le ṣe eyikeyi ninu rẹ, ki o dubulẹ ki o si ma fi ipenpeju rẹ ki i. Bi eyi na pelu ko ba ṣeṣe, ti laakaye rẹ si wa sibẹ, ma fi ọkan ki i, ki o si ma ṣe Alahu Akbaru sinu ikẹ. Nitori akoko ni kewu, akiku ni irun, ẹniti Ọlọrun ba kọ ni yio kọ irun kiki silẹ.

## Ode Kan Pitan Kiniun

Emi gẹgẹbi ọdẹ igbo, irohin ti mo le fun yin nipa ẹranko Kiniun niyi:-

Kiniun jẹ ẹranko kan ti o ni agbara, o laiya. Ko si si ohun kan ti o mba a lẹru ẹgungun rẹ ko ni iho ninu. Ko si ohun ti o le ma bọwa ti o jẹ titori rẹ kuro nibiti o wa, Kiniun a ma so wipe, emi ni ọba awọn ẹranko. Oko wa ode lati fi mi han bi ọba, mo lọwọ meji, ati ẹsẹ meji, mo le fi ikaka mi kan lu enia pa.

## ANFE ASOJU

A nfẹ Aṣoju fun Iwe Irohin wa Eleti-Ọfẹ lati fi kun awọn Aṣoju wa ni awọn ilu ti a darukọ ni isalẹ wọnyi:-

Abẹokuta, Ijẹbu-Ode, Ijẹbu-Igbo, Ile-Ifẹ, Oshogbo, ati Port Harcourt.

E kọwe si Olotu Iwe Irohin Eleti-Ọfẹ, 28, Kosọkọ St. Lagos.




Nje ojo ba fun o ni irora lakuregbe bi? Fi egbogi yi wo ibi ti o dun o.

ELECTRIC Balm



# Awọn Alhadji Ibadan ko Adelabu

IBADAN. A gbọ irohin wipe awọn awujọ Alhdaji ti o wa ni ilu Ibadan kọ lati gba Ọgbẹni Adegoke Adelabu sinu agbo wọn, gẹgẹbi ọkan ninu awọn ti o lọ si Mẹka ti o pada bọ.

Pantiwa ?. Baba Issiẹ Ijọ Musulumi Ibadan sọ wipe, awọn ko le gba Adelabu ni Alhadji, nitoripe, o kan lọ mọ ilẹ Arabia ni. Oloye na sọ wipe, ọrọ ẹsin ni ẹgbẹ Alhadji Ibadan fi ara mọ, ṣugbọn Adelabu fẹ ko iṣẹ iṣelu wọ inu ijọ na.

Bi Alhadji kan ba fẹ de gẹgẹbi aṣa, o ni lati ranṣẹ iye ọjọ ti yio de, gbogbo awọn Alhadji yio si lọ pade rẹ, Adelabu ko ṣe bẹ. Ko nṣe aṣa wipe ki Alhadji kan to ṣẹṣẹ de kirun ọpẹ ni ẹsẹ Mọṣalaṣi, ṣugbọn Adegoke kirun si ni ẹsẹ Mọṣalaṣi.

Imam Jamiyu ilu Ibadan sọ wipe, on ko le sọpe tulasi ki awọn gba Adelabu sinu awujọ Alhadji nitori awọn ni Olori tiwọn lọtọ. Ṣugbọn eyiti on ri nibẹ ni wipe Adelabu fi oju di wọn nipe alaini fun wọn nigbati yio fi de, ti o si lọ ṣeto ara rẹ funra rẹ. "Eyi ni ko ni jẹki a gba Adelabu gẹgẹbi Alhadji ti ti yio fi ṣujada.

Adelabu sọ wipe, on si nfẹ ki riti-riti yi rọlẹ na. Awọn ẹlomiran sọ wipe eyiti Adelabu fẹ ṣe yi ko dara ọrọ na kan koko o si fẹ ero nitori ọtẹ titun miran le ti ibẹ gberan larin awọn Musulumi.

"The English Association of Accountants & Auditors.
The English Association of Estate Agents & Valuer.
The English Association of Secretaries.
Founded 1941. Membership on Professional Experience, of Certificate with Reputable Schools Colleges, Universities"
9, Charles St. Newport, Mon, Eng.

# Ọbọ, lagido, eja a fewe pa

Ọkunrin alagbara kan so ọbọ mọlẹ, o si joko nworan ọbọ na bi o ti nṣe, o nrẹrin on nikan, gbogbo awọn enia ti nkọja lọ si nwo baba ti on nikan rẹrin yi, awọn enia ko kuku mọ ohun ti o npa a lẹrin.

Bẹni ọmọ ilewe kan mbọ wa, o ri baba ti o nda rẹrin funra rẹ yi. O si wipe, Ṣiọ! Ọbọ, lagido, idanda, ẹja afewe pa. Kini baba na gbọ bayi si, ori rẹ gbona o dide kia o yọ atori; o si ko bo ọmọ na. Ọrọ yi si di akitiyan ti o ni lati de kota.

Ọkunrin na rojọ wipe, on ko mọ ọmọde na tẹlẹ ri ayafi bi o ti mbọ, lo wo on ṣuṣu, o sin itọ, o si wipe Ṣiọ! ọbọ, lagido. Emi agbalagba, kini mo fi ṣe ki o to ma pe mi ni ọbọ, lagido. Nigbati o wi ti ẹnu rẹ tan, adajọ bere lọwọ ọmọ na pe pantiwa ?.

Ọmọ na dahun pe, li otitọ ni on sọ wipe ọbọ; lagido, nitoripe lọjọ na on ri ti o so ọbọ (Monkey) mọlẹ ti o si npa baba alagba yi lẹrin; eyi lo jẹ nkan iyanu fun on, ti on fi wipe ṣiọ! ọbọ, lagido. Gbogbo awọn enia si ṣe ha!. Adajọ ni ki baba na lọ san ẹgun Pọun fun ọmọ na fun lilu ti o lu u.

Kere o!

A ti ni origirisi ogun German to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Yete wa ra tirẹ k'o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS
MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos.

# Onimoto Nte jeje



Nigba lailai, ẹnitì ko ba ni ile ibiti yio fi mọto rẹ pamọ si, ko gbọdọ ra mọto. Eyi ni (Garage) ṣugbọn latigba ti nwọn ti mu ofin yi kuro ni mọto ti bẹrẹ si pọ si nilu.

Lasiko yi, nisisiyi ko si ọkọ kan ti yio de si Apapa ti ko ni gbe mọto bi mẹwa sokalẹ. Ninu aworan eke yi, ni a ti ri ọkọ oyinbo kan ti o jẹ wipe; ko si ohun meji ti o ko wa, bikoṣe ẹru Mọto.

Awọn mọto rẹpẹtẹ ti a nwo lori kereni nwọnyi koiti pọ to idaji eyiti ọkọ na ko gunlẹ bẹni gbogbo nwọnyi na, nilẹ Nigeria yi lo mbọ.

Kini ẹ ti rope yio ri nigbati iru ọpọ mọto nwọnyi ba nrinlọ-rinbọ, loni lọla ati lọtunla loju opopo kanna, nighawo ni ọna ko ni bajẹ? Ejọ ko nṣe ejọ Town Council bẹni ko nṣe ejọ P.WD.

Nitori nigbati ojo koiti rọ, ẹnikan ko ri ẹjọ kan wi, ṣugbọn bi ko ba si ti ṣgbẹ ọmọri odo ko nlu iya rẹ lasan, nitoriti ojo ọdunni ti o pọju lo fa ti agbara fi bẹrẹ si sọ oju ile di riro, eyiti ẹsẹ mọto fi bẹrẹ si bu awọn okuta ibe s'oke, te o nṣe ejọ Lagos Town Council.

No. 73/S 2/Vol VIII/471

# Inland Revenue Department, Ministry of Finance Western Region

## Vacancy For Clerical Officers

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment in the Department of Inland Revenue. Ministry of Finance. Western Region, Ibadan, as Clerical Officers.

Particulars of the Posts are as follows :-

(i) Vacant office — Clerical Officers.
(ii) Scale of Salary — D 1, 2, 3: £150 x 6 - 162 x £18 - 180 x 9 - 234 x 12 - 330 x 15 - 360.

(iii) conditions of service. - The post is pensionable and appointment will be on probation for three years in the case of new entrants into the Government service.

Qualifications. - Candidates should possess one of the following minimum educational qualifications provided they include a pass in English.

(a) Cambridge School Certificate;
(b) West African School Certificate; or
(c) General Certificate of Education, Ordinary Level with a pass in at least three subjects.

Methods of application. - Applications accompanied by copies of School Leaving Certificates and Testimonials should be addressed to the Commissioner of Inland Revenue, Ministry of Finance, Western Region, Ibadan, not later than the 10th of August, 1957. Applications from officers already in the Goverment services should be submitted through the Heads of applicants' Departments accompanied by copies of confidential reports on the new Confidential Report Form Secretariat 72.

## Ise Alabiyamo (Nurses)



Aworan ti e nwo yi ni edomobinrin kan. omo ile Nigeria ti o npe Matilda Ikomi ti o lo ko ise igbebi ati ise alabiyamo nile alabiyamo nla kan nilu Oyinbo ti nwon npe ni St. Olave's Rotherhithe.

Gbogbo awon omo akeko ti o ba wa lati ile Kanada, Nigeria, Ghana, Jamaica, Barbados, Ile Faranse, Panyan ati ile Griki lati wa eko yi; ibe ni a ti nko won papo, ti nwon si ntise po pelu ife.

Matilda na lo nse itoju omo ekee kan ninu ile alabiyamo na.

# Oku Olomo Gege L'ao gbe

EKO:- Ni ojo Abameta ti ise ojo ketala osu keje odun yi (13/7/57) 'ni Iya alagba oninure Animotu Pedro, eniti a mo adape oruko re ni "Iya-Onigbanjo" jalaisi ninu ile re, 4, Erinle Street, Isalegangan, l'Eko, nigbati o gun oke agba di eni adorun odun laiye.

Ki Iya na to faiye sile ni Rasaki Pedro, eniti a mo adape oruko re ni, Baba Asi, ni igboro Accra ti de S'eko. Gegebi ilana esin Ojisenla Muhamodu, Imam Abibulai Adetoro, pelu awon Saraki adjeni igun merer[illegible] Eko, lo peju pese se isin ikehin fun iya na.

Lehin isin yi ni awon Omo-oloku awon bi:- Alufa Semiseliu Pedro, Rasaki Pedro Ashake Pedro, Rasidi Pedro Amudatu Pedro, Asinatu Pedro. Adamo Pedro, Mutalabi Pedro, ati awon aromodomo titi kan awon ore bi:- T.S. Adewale, Y.A. Fashola omo-Oba Adeniran Adefarakan ati awon ti aye ko si lati daruko won sibi tan. nfi jije ati mimu te gb gbo awon olubaseye nibi oku na lorun.

Ninu isin ikehin Oku iya na, Imam Adetoro, jeri si wipe, iya na je enikan pataki ninu awon to fese rinle girigiri fun esin Ojisenla Muhamodu, ninu Mosalasi Isalegangan ati wipe o je olutore ati oloyaya enia t'o ko t'omode t'agba mora nigba aiye re, Ki Oluwa ko pa asise re re, ki Oluwa se e ni omo Alijanna. Iya Rasaki, Orunre o.

## Owe Yoruba

Ekolo nmi gbogbo inu mbi adie susu. adaba ko nani a nkungbe rara, bi ina ti njo ni eiye oko nlo.






## Oku Tiko Ku S'omi Nm'okunkun Ni Sare

(O bẹrẹ loju ewe kini)

Awọn ọmọ oloku wọnyi njẹ, nwọn si nmu, ṣugbọn nwọn ti gbagbe awọn ẹniti o sẹ won silẹ, ti wọn si fi ogun owo tabi ohun alumọni pataki silẹ fun wọn eyiti awọn ọmọ oloku be njẹ ọla rẹ.

Oku ti ko ku s'omi nm'okunkun ninu odo Sare.

## Okunrin kan lu Olopa pa ni Surulere

SURULERE. Awọn ọlọpa mu ọkunrin kan fun ẹsun olo jija, nwọn wa yan ọlọpa kan, Samuel Adeṣina lati tọle ọdaran na ti nwọn npe ni Joṣua Ngurlbe-lati lọ ṣe iwadi bi ọrọ na ti lọ.

Nigbati nwọn de oju ọna ọkunrin ọdaran na sa mọ ọlọpa yi lọwọ, a gbọ pe nibi ti ọlọpa gbe nle ọdaran na ninu igbo, ni o gbe yiju pada si ọlọpa na, a si gbọ pe o lu u pa. Nigbati nwọn reti ti ọlọpa na ko de, ni nwọn ba da awọn ọlọpa sinu igbo Surulere, nwọn si kan ọdaran ti on pẹlu ọlọpa lọ ni Ibidun Street, nwọn ri oku ọlọpa ni Alufa Atarẹ Street ninu igbo bi iwọn ọdunrun ọpa si Surulere.

Gbara ti ọdaran yi foju kan awọn ọlọpa lo ba gun ori oke lọ gbogbo ọlọpa ti o ba fẹ lọ ba lo nna nigi ṣugbọn nigbati awọn Panapana de ni nwọn ba ki i mọle. O mbẹ nikawọ awọn ọlọpa, nwọn nṣe iwadi lọwọ.

## Alakoso Elet-Ọfe Re Ajo

Ọgbẹni Taju Thompson ti o nṣe Alakoso iwe iro-hin Eleti-Ọfẹ da kan lọ bẹ ilu Ibadan wo, ko si ni pẹ pada.

Alọ a dara abọ a sunwọn o

## Eje ki a lo jo

Idaraya kekere kọ lo wa ninu ijo, paapa ni asiko oworẹ yi. Bi enia ie ti o si mu tan, o yẹ ki oluwarẹ wa ehun kan ti yio fi ṣe idaraya, orişirişi ọna ni o wa ti enia le fi ṣe idaraya. Bi awọn kan ti nsare ije bẹni awọn miran yio ma fo, awọn mi-ran ẹwẹ, ama jo. Igbadun pupọ l'o wa ninu ijo ni asiko ode oni.

Bi o ba di ọjọ Satide ti o mbọ, ọjọ kẹta oşu August; 1957; awọn Oyinbo ti o nta Şokeleti "Mu ọkan tutu" (Lyons Ice Cream) yio tẹ itafo ijo nla kan ni Idi-Oro; Lido Bar, nibiti nwọn ti pe ọpọlọpọ awọn saamori enia si. Wọn nfẹ ki olukuluku wa ya ọjọ yi s'ọtọ fun ariya wọn. Alaiyeluwa Ọba Adele keji ni yio ṣe alaga ọjọ na.

Awọn Oyinbo Lyons yio fi ọja wọn dabira ni ọjọ na. Ijo ọjọ yi yio pa bambari. Bi o ba nfi apa jo bẹna ni o si ma fi ọwọ kan toku mu M'ọkantutu (Lyons Ice Cream). Igbadun rẹ ko kere, ọrẹ mi: jẹki a ba wọn debẹ.

## Alhaji Kan Kowe Sile Lati Mecca

Alhaji kan ti o ni orukọ on rẹ Alhaji Ọmọke wu ni ẹniti a ri wesika yi gba lati ọwọ rẹ ni ilu Mẹkka (Mecca). Ẹnyin na ẹ ba wa ka:

Olotu,

Alagba, mo fẹran lati ma ka iwe rẹ Eleti-Ọfẹ ki nto kuro nile wa si ilu Mẹkka yi, ṣugbọn o ti to oşu meji nisisiyi ti mo ti ri ikan gbẹhin. Ni Mẹkka ni mo wa loni.

Boya ki wosika yi to tẹ yin lọwọ, emi na a ti de Mẹdina. Mo dupẹ lọwọ Ọlọrun, mo ti gun Oke Arafa ni ana ọjọ reec. Yagbo-yaju ni ọrọ Mẹkka ti ọdunni. Enia pọ tobẹ gẹ ti o fi jẹ wipe Arabu kan ti mo agbe ile rẹ sọ wipe Ọlọrun lo gbadura awọn, nitori iṣe ikore ti awọn ni ọdọdun niyẹn, awọn ko ṣa ni Koko (cocoa) ti oyinbo agba. Bi ẹnyin ba ti nwa to bẹna ni owo ṣe nwọle fun awọn.

Mo bi lere nigbawo ni diẹ ninu awọn na yio wa mọ ilu wa, o ni efin ilu awọn ko gba awọn laye ati ma jade kiri.

Olotu, ko si ibiti iṣẹ ati ebi ko si, ebi pọ nile Mẹkka o. Gbogbo ọrọ lori owo ni. Mo ri Adelabu ọmọ Ibadan, minista Adegbenro pẹlu Sardauna nib ti nwọn gbe de si. Gbogbo wa bakanna ni a jọ ri nibi. Ngo sọ iyoku ti mo ba de ile

### ỌKUNRIN KAN YUN-ỌRUN-BỌ

Ọkunrin Oşiṣẹ kan ti o mba wọn mọ ile efin (Funnel) iru ti ile iṣẹ Lantiriki ni Ijọra loşeşi ṣubu sinu ibo ile efin na ti o ga to igba ese, ko si ku, bi a ba bere lọwọ rẹ kini ọna ọrun ti ri yio sọ diẹ.

## Awon Omo Ile Hausa Nilu Oyinbo



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni awọn ọmọ ile Hausa ti a fun ni anfani ẹkọ ọlọfẹ lati lọ kọ iṣẹ nilu Oyinbo. Orukọ wọn niwọnyi:-
1 Akila Todi, (Pastor) 2 Orban Lang (Councilor)
3 Malam Bomai, 4 Umoru.





ARADAN NERVIGORA

Ogun ẹjẹ pataki fun imarale agba ati arẹmọ pipe fun awọn alaya pupọ. O dara fun inarun, ẹjẹ dudu, işokun oju, gbigbọn ọwọ, ailesun, ailokun ninu, ati irufẹ arun bawọnni. O jẹ ajidewe fun awọn ti agbara wọn ndinku. On na gan ni ọkunrin yi lo ti o fi di "Afẹsọkun bi ojo." 5/6d. pere pẹlu owo ọkọ 1/6d e.g. 7/- Post Free.

**The Egba Trading Aradan Stores**
112, Denton Street, 18, Denton Bridge Street, P. O. Box 2. Ebute - Metta.
Phone 44153. A tun wa ni New Motor Park (Ogunpa) Ibadan.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 25, Kosoko Street P. Box 487 Lagos Phone 23390